# NÀÌJÍRÍÀ | NIGERIA

TIER 1 | USCIRF-RECOMMENDED COUNTRY OF PARTICULAR CONCERN (CPC)

Ìgbìmọ Òlómìnira Ẹ̀sìn Lágbàáyé ti U.S (USCIRF) jẹ́ olómìnira, ìgbìmọ̀ aláfẹnukò òṣèlú ìjọba àpapọ̀ ti U.S tí Àjọ Olómìnira Ẹ̀sìn Lágbàáye 1998 (IRFA) tó ń bójútó ẹ̀tọ́ gbogbogbò fún òmìnira ẹ̀sìn tàbí ìgbàgbọ lẹ̀yìn odi ṣẹ̀dá. USCIRF máa ń lo àwọn àfẹnukò àgbáyé láti ṣàbójútó àwọn ìrúfin òmìnira ẹ̀sìn tàbí ìgbàgbọ lẹ́yìn odi tí wọ́n sì máa ń ṣe ìdámọ̀ràn ìlànà fún ààrẹ, àkọwé ìpínlẹ̀, àti Àwọn aṣòfin. USCIRF jẹ́ àjọ olómìnira tó dá dúró tí ó sì dáyàtọ sí Ẹ̀kà Ìpínlẹ̀ U.S. Ìjábọ Ọlọ́dọọdún 2018 jẹ́ àpapọ iṣẹ́ ọlọ́dún kan nípaṣẹ̀ Àwọn alákòóso iṣẹ́ àti òṣìṣẹ́ akọ̀ṣẹ́mọṣẹ́ lati ṣe àkọọlẹ̀ àwọn ìwàkiwà tó wà àti láti é ṣe ìdámọ̀ràn àwọn ìlànà fún ìjọba U.S. Ìjábọ Ọlọ́dọọdún wà fún Ìjábọ láti January 2017 sí December 2017, lóòótọ ní ìgbà míràn àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó bá ṣe pàtàkì tí ó wáyé kí ó tó di àkókò yìí tàbí lẹ̀yìn àkókò yìí ní a mẹ́nubà. Fún ọpọ ìwífún nípa USCIRF, wo ojú òpó wẹ̀ẹ̀bù níbí, tàbí kàn sí USCIRF tààràtà ní 202-523-3240.

## Nàíjíríà

**Àrígbamú Pàtàkì:** Ìpò òmìnira ẹ̀sìn ní Nàìjíríà jẹ́ èyí tí ó kù díẹ̀ káàtó ní 2017. Ìjọba Náìjíríà ní àwọn ìpele àpapọ àti ti ìpínlẹ̀ tẹ̀síwájú láti fi ààyè gba ìdálúrú àti ẹlẹ́yàmẹ̀yà lórí ọrọ ẹ̀sìn àti ìgbàgbọ, tí wọn kò sì fi ààyè gba ìgbélárugẹ òminira ẹ̀ṣìn tàbí ìgbàgbọ. Ìjọba àpapọ tẹ̀síwájú láti fi olórí ẹ̀ṣìm Shi'a Islamic Movement of Nigeria (IMN), Sheikh Ibrahim Zakzaky, pẹ̀lú ìyàwó àti ogúnlọgọ àwọn ọmọ ẹ̀yìn rẹ̀, àtipé ìjọba ìpínlẹ̀ tẹ̀síwájú láti fi òfin de àwọn àkitiyan ẹgbẹ́ náà. Ìdálúrú ẹlẹ̀yàmẹ̀yà láàrin kíkìdá àwọn músùlúmi dárandaran àti kíkìdá onígbagbọ tí wọ́n jẹ́ àgbẹ̀ ń pọ síi, àti pé ìjọba àpapọ Nàìjíríà kùnà láti ṣe àmúṣe ètò tó múná dóko láti dénà tàbí dá irú ìdálúrú náà dúró tàbí lát fí àwọn àdàlúrú náà jófin. Láì fi àṣeyọrí tí àwọn ológun Náìjíríà ṣe nípa ìjà wọn pẹ̀lú Boko Haram, àìṣapá ìjọba nípa lílo àwọn ọmọ ogun ń wáyé, àtipé ìkọlú Boko Haram sì ń tẹ̀síwájú. Ìjọba náà kùnà láti fí àwọn ọga sọ́jà Ológún Náìjíríà kan jófin fún àsìlò agbara àti ìfiyajẹni láìbófinmu sí àwọn ọmọ ẹgbẹ́ IMN, sí Boko Haram, àti nípa ìṣapa wọn láti dín jàgídíjàgan ẹlẹ̀yàmẹ̀yà kù. Lákòótán, àwọn ìwàkiwà sí òmìnira ẹ̀sìn tẹ̀síwájú ní ìpele ti ìpínlẹ̀, gẹ́gẹ́bíi òṣìṣẹ́ àfipámúni tàbí àwọn ìgbéṣẹ̀ àwùjọ láti fi ipa fà ẹ̀sìn kalẹ̀. Nítorí àwọn ìrúfin tí a ti kà sílẹ̀ wọ̀nyìí, ní 2018, USCIRF tún rí pé ó yẹ kí Náìjíríà wà lára àwọn orílẹ̀-èdè tí a mọ sí "orílẹ̀-èdè ìbanikẹ́dùn nípàtó" tàbí CPC, lábẹ́ Àjọ Olómìnira Ẹ̀sìn Lágbàáyé (IRFA), bí wọ́n ṣe ṣèdásílẹ̀ rẹ̀ ní 2009.

**Àwọn ìmọ̀ràn ìlànà fún Ìjọba U.S.**

- Yíyan Nàíjíríà gẹ́gẹ́bí CPC lábẹ́ IRFA;

- Wíwá ààyè láti ṣe àdéhùn pẹ̀lú ìjọba Nàíjíríà, gẹ́gẹ́bí ìfàṣẹsí lábẹ́ẹ abala 405 (c) ti IRFA, kí ìpèsè àtìlẹyìn ìnáwo àti ìmọ ìjìnlẹ̀ tí ó jẹ́ mọ, láti pa ní dandan fún ìjọba Nàíjíríà látí gbé ìgbéṣẹ̀ tó ní láárí lórí àwọn ìrúfin òminira ẹ̀sìn, gẹ́gẹ́bii:
    - Fífún àwọn ọlọpa tí a ti yàsọtọ àti àwọn òṣìṣẹ́ aláàbò ní ìdanilẹ́kọọ àti sísọ wọn di akọṣẹ́mọṣẹ́ láti lé dá ààbò bo ìlú lọwọ jàgídíjàgan ẹlẹ́yàmẹ̀yà àti ìwá ìdẹ́rúbalú, bíi ìdójú ìjà kọ àwọn àdẹ́rùbàlú, ọgbọn ìwádìí, àmójútó ààbò láwùjọ, dídárí ọpọ èrò láì mú ìpalára dani, àti ìlànà ìdènà ogun láwùjọ;
    - Mímú ìdàgbàsókè bá ìdánilẹ́kọọ fún àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba ológun àti ọlọpàá lórí i àwọn àfẹnukò ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lágbàáyé, àti mímú dájú pé àwọn òṣìṣẹ́ ààbò tí ó bá si agbara lò lọnà àìbófinmu àti àwọn ìrúfin ẹ̀tọ ọmọnìyàn ní ìjọbá máa wádìí tí wọn ó sì fi jófin;
    - Ṣíṣe àwọn ìwádìí tó jinlẹ̀ ní ìlànà òfin àti lílo ìlànà òfin lóríi àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ jàgídíjàgan ẹlẹ́yàmẹ̀yà àti ìfogundẹ́rùbàlú pẹ̀lú fífi àwọn arúfin/jófin;
    - Ṣíṣe ìmúdàgbà ìdènà tó níláárí àti ìlànà ìkìlọ ní ìpele ìjọba ìbílẹ̀, ìpínlẹ̀, ati àpapọ nípa lílo ìlànà tó ṣée ṣàmúlò lọnà tó rọrùn;
    - Gbígba àwọn olóṣèlú àti àwọn olórí ẹ̀ṣìn níyànjú láti kópa nínu àkànṣe iṣẹ́ àti ìdánilẹ́kọọ ìṣàkọso èdè-àìyedè láti dènà jàgídíjàgan, àti àwọn ọrọ kòbákùngbé;
    - Gbígba ìjòba Nàìjíríà nímọ̀ràn àti ṣíṣe àtìlẹyìn fún ìjọba nípa ìdàgbàsókè àwọn ètò àgbàlúlọwọ-ogún àti àmúlùtòrò;

- Ṣíṣe ìpàdé ìgbìmọ orílẹ̀-èdè U.S.-Nàìjíríà láti jíròrò àwọn ìgbéṣẹ̀ láti fòpin sí jàgídíjàgan ẹlẹ̀yàmẹ̀yà, ṣísọrọ lórí ìṣòró ìlẹ̀, fífi àrúfin jófin, àtí pípari ìjá lárín àwújọ kan sí èkejì;

- Ríri dájú pé àwọn ìṣòro òmìnira ẹ̀ṣìn ní Àwọn àṣòfin gbéyẹ̀wò lábẹ́ẹ abala 1279A tí Àjọ Ìfàṣẹsí Ààbò Orílẹ̀-èdè fún Ètò ìnáwó Ọdún 2018, pẹ̀lú nípa:
    - Ṣíṣàyẹ̀wò ojúṣe ìdánimọ ẹ̀sìn nínú àwọn ìrúfin ẹ̀tọ ọmọnìyàn nípaṣẹ̀ Àwọn ẹ̀sọ aláabò Nàíjíríà;
    - Ṣíṣàyẹ̀wò ìdásí àwọn olórí ẹ̀sìn nípaṣẹ̀ àwọn ẹ̀sọ aláàbò Nàíjíríà láti le ṣàmúdágbà ìdábòbò àwọn ará ìlú;
    - Fífi ẹ̀kọ àti ìdáníl ẹ̀kọọ lórí àwọn ìṣòro òmìnira ẹ̀sìn sí èròǹgbà fún ìjọba U.S láti le ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn ẹka ìlé iṣẹ́ ìjọba Nàìjíríà kí wọn le ṣètò láti mú ìpò tí àwọn tó wà láhàámọ dára síí;

- Láàrin ìrànlọwọ U.S. sí Nàíjíríà lọwọlọwọ, àlékún ìrànwọ owó àti àtìlẹyìn fún ìṣàkóso àti ìdènà èdè-àìyedè ní àwọn ìpínlẹ̀ ààrin gbùngbùn àti àríwá tí wọn ń dojúkọ wàhalà ńlá

nípa jàgídíjàgan ẹlẹ́yàmẹ̀yà, àti fún ìwádìí sí ìbáṣepọ láàrin ìkọwó ìlú jẹ àti àwọn ìrúfin òmìnira ẹ̀ṣìn ní Nàìjíríà; àti

- Lo àwọn ìrńṣẹ́ áfojúsùn ní ìlòdì sí àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba àti àwọn ilé iṣẹ́ kan tí a ti ṣèdámọ̀ rẹ̀ gẹ́gẹ́bí ẹnití ó ti kópa tàbí tí ó mọ̀ nípa ìwàkiwà nípa ìrúfin ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, gẹ́gẹ́bí ìrúfin òminira ẹ̀ṣìn. Àwọn ìrinṣẹ́ wọ̀nyìí jẹ́ bíi "Àwọn orílẹ̀-èdè tí a ti yàn sọ́tọ̀" tí àtòkọ rẹ̀ wà ní àbójúto U.S. Department of the Treasury's Office of Foreign Assets Control, ìkọ̀fúnnì àvisa físà lábẹ́ẹ 604(a) ti IRFA àti the Global Magnitsky Human Rights Accountability Act, àti ìgbẹ́ṣẹ̀lé dúkíà lábẹ́ẹ the Global Magnitsky Act.

## Ìrísí

**Nàìjíríà**
**Full Name:** Ìlẹ̀ Olómìnira Nàìjíríà
**Government:** Òlómìnira Ààrẹ
**Population:** 190,632,261
**Government-Ẹ̀ṣìn/Ìgbàgbọ tí ìlú gbà wọlé:** N/A
**Ẹ̀ṣìn *:**
50% Mùsùlùmí
40% Ìgbàgbọ
10% Ẹ̀sìn àbáláyé

*Láti inú àkọọlẹ̀ CIA World Factbook

Pẹ̀lú oríṣiríṣi ẹ̀yà àti èdè àti ìpayà ọlọjọpípẹ́ pé ó ṣeéṣe kí àwọn ẹ̀yà tàbí ẹ̀ṣìn kan bo àwọn ẹ̀yà tàbí ẹ̀ṣìn míràn mọlẹ̀, ìjọba Nàìjíríà ń ṣètò láti ṣàgbéga ìsọkan orílẹ̀ èdè tí ó sì ń ṣe akitiyan láti má jẹ́ kí ẹ̀yà tàbí ẹ̀ṣìn kan kí ó bó òmíràn mọlẹ̀ àti láti dẹ́kún jàgídíjàgan ẹlẹ̀yàmẹ̀yà. Ìwé ofin Nàìjíríà ti 1999 ní àwọn ìpèsè ìdáàbòbò òmìnira ẹ̀sìn tí ó sí fi òfin de ẹ̀ṣìn bárakú. Ìwé ofin náà fààyè agbára sílẹ̀ fún ìlàna ìpídọgba ìjọba àpapọ, èyí tí o ṣàrídájú pé onírúurú ẹ̀yà àti ẹ̀ṣìn ni ìjọba wà fún, Ìgbìmọ Ìṣesí Àpapọ máa ń gbìyànjú láti ríi dáju pé ó pèsè àwọn asojú sí ilé iṣẹ́ ìjọba gẹ́gẹ́bíi ọlọpàá, ológun, àti àwọn ilé iṣẹ́ ìjọba mìíràn, àti láti ríi dájú pé pínpín ohun àmúṣọrọ àti àwọn ìpèsè wá ní dọ́gbadọ́gba. Síbẹ̀síbẹ̀, nítorípé ìlánà yìí wà ní ìṣàmúlò lórí ìlànà "ọmọ-onílẹ̀", èyí tí ó jẹ́ pé àwọn kan ní a ms sí ọmọ onílẹ̀ sí àwọn agbègbè kan àtipé fún ìdí èyí wọn ní ẹ̀tọ àti àǹfààni tí kò sí fún àwón tí kìí ṣe ọmọ onílẹ̀ tàbí "àjèjì", àwọn kan wà tí wọn kò ní ẹ̀tọ tó dọgba ní àwọn agbègbè kan ní ìjọba ìbílẹ̀. Pẹ̀lú ìtàn, àwọn èèyàn tó wà ní àríwá jẹ́ kìkìdá mùsùlùmí nígbàtí àw\n ènìyàn tó wà ní gúúsù jẹ́ kìkìdá oígbàgbọ.

Ní Nàìjíríà, àwọn ọba àti olórí ẹ̀sìn sì ní ìpa ribiribi tí wọn ń kó nínú òṣèlu àti ìṣèjọba, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn olórí ẹ̀sìn jìyàn pé àwọn kò ní aṣojú to nínú ìṣejọba. Nínú àwọn ìpínlẹ̀ Nàìjíríà 12 tí ó jẹ́ kìkìdá mùsùlùmí, Ìdàjọbapọ wọn ti fi ààyè gba òfin Shari'ah nínú ìṣèdájọ ọ̀daran. Ọlọpàá ẹ̀ṣìn wà fún gbígbé òfin Shari'ah dúró èyí tí ó mójútí ọrọ ẹbí àti ìhùwàsí ẹ̀dà jùlọ.

Fún ọpọlọpọ ọdún ṣẹ́yìn, Nàìjíríà tí gbiyànjú láti yanju ìṣòro jàgídíjàgan ẹlẹ́yàmẹ̀yà láàrin àwùjọ àwọn àgbẹ̀ àti darandaran tí wọn yàtọ gédégédé nínú ìlànà ẹ̀ṣìn. Àwọn ìròyìn àsọdùn náà tún dàkún wàhálà tó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀, àtipé 2017 jẹ́ ọdún tí jàgídíjàgan wọpọ jùlọ ní àwọn àwùjọ yìí bí a bá wòó sí àwọn ọdún tó ti kọjá. Àwọn ìkọlù nípaṣẹ̀ ẹgbẹ́ àfogundẹrùbàlú Boko Haram, tí ó bẹ̀rẹ̀ ní 2009, ń tẹ̀síwájú láì wo akitiyan ìtẹ̀síwájú ìjọba Nàìjíría lórí gbógbógun ti ẹgbẹ́ adẹ́rùbàlú. Nípaṣẹ̀ ìpolongo oníjàgídíjàgan lórí ẹ̀sìn mùsùlùmí ní Nàìjíríà àti ní Lake Chad Basin, Bokò Haram ló pa àìmọye ènìyàn, wọn jí ọpọlọpọ ènìyàn gbé, wọn sì lé ènìyàn bíi mílíọnù méji kúrò láàyè wọn. Báknnáà, ìjà darandaran tí ó ṣẹlẹ̀ ní ààringbùngbùn Nàìjíríà tí já sí lílé àwọn ọps ènìyàn kúrò láàyè wọn, ọ̀pọ̀ dúkìá ti parun, ọ̀pọ̀ ènìyàn sì kú lẹ́gbẹ̀rún lẹ́gbẹ̀rún.

Ikọ USCIRF rin ìrìnàjò sí Nàìjíríà ní January àti February 2017, Wọn ṣàbẹ̀wò sí àbújá àti kàdúná láti ṣèpàdé pẹ̀lú àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba, àwọn ẹlẹ́ṣin, àti ẹlẹ́gbẹ́jẹgbẹ́ láàrín ìlú.

## Ìpò Òmìnira Ẹ̀ṣìn 2017

***Ìfagbaratẹ̀mọlẹ̀ Islamic Movement of Nigeria:*** IMN, tó jẹ́ ẹgbẹ́ Músùlúmí Shi’a tó pọ jùlọ ní orílẹ̀ èdè, Sheikh Ibrahim Al Zakzaky ní ó dáa sílẹ̀ ní àríwá ìlú Zaria ni Ìpínlẹ̀ Kaduna ní ọdún 1980 sí 90, pẹ̀lú èròńgbà láti dá ìpínlẹ̀ mùsùlùmí sílẹ̀. Ẹgbẹ́ náà ítàn jàgídíjàgan pẹ̀lú àwọn ẹ̀sọ aláàbò Nàìjíríà àti mùsùlùmí Sunni. Lóòótọ ẹgbẹ́ náà ní àwọn ti fi jàgídíjàgan sílẹ̀, ìjọba Nàìjíríà sì ń tẹ̀síwájú láti fi wọn sí ìsọrí ẹgbẹ́ oníjàgídíjàgan tí wọ́n sì ń lo àgbára àlòjù láti fòpin sí ẹgbẹ́ àti àkitiyan ẹgbẹ́ náà.

Lẹ́yìn bí ọdún méjì àti díẹ̀ tí ìjọbá ti fi ìpa àti jàgídíjàgan mú ẹgbẹ́ IMN walẹ̀—pípa àti sísin àwọn ọmọ ẹgbẹ́ IMN 347 lápapọ eyí tí àwọn ológún Nàìjíríà ṣe ní Zaria ni December 2015—àtipé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìgbímọ ìwàdìí Ìpínlẹ̀ Kaduna jábọ pé àwọn ológun jẹ̀bi àtipé ki wọn fojú ba ilé ẹjọ, kò sí ọkankan nínú àwọn ọga ológun náà tí ìjọba fi jófin. Àwọn ọlọpàá Nàìjíríà náa sì tẹ̀síwájú láti fi ogúnlọgọ àwọn ọmọ ẹgbẹ́ IMN sí àhámọ—pẹ̀lú, ẹni tí ó jẹ́ gbajúgbajà, Sheikh Al Zakzaky àti ìyàwó rẹ Malama Zeenah Ibrahim, tí wọn fi wọn pamọ láì fẹ̀sùn kàn wọn, ní ìlòdi sí àṣẹ tí ó wá láti Ilé ẹjọ Gíga Àpapọ ní àbújá pé kí wọn fi wọn sílẹ̀ láàrin ọjọ́ 45 bẹ̀rẹ̀ láti December 2, 2016. Wọ́n ṣe Zakzaky léṣe, àtípé ọmọ rẹ̀ mẹ́tà ni wọn pa, nínú ìkọlù December 2015. Ní March 2017, àti ní ìdáhùn sí ohun tí ara ìlú ń sọ nípa àìtẹ̀lé ẹ̀tọ ọmọnìyan láti ọdọ àwọn ẹgbẹ́ tí wọn ń jà fún ẹ̀tọ ọmọnìyàn, Ilé ìṣẹ́ ìjọbá tí ó ń rí sí Ọrọ Ilẹ̀ Òkèèrè ní pe ẹjọ Zakzaky ní “ohun ẹlẹgẹ́ tó níiṣe pẹ̀lú ààbò ìlu”; òun àti ìyàwó rẹ̀ sì tún wà lẹ́wọn lẹ́yìn ọjọ́ tí ilé ẹjọ dá.

Ní gbogbo 2017, àwọn ọmọ ẹgbẹ́ IMN ṣe ìwọde káàkiri orílẹ̀ èdè tí wọ́n ń fẹ́ ìtúṣílẹ̀ Zakzaky. Ní Kàdúná àti Sokoto, àwọn àkitiyan wọn, gẹ́gẹ́bíi ìwọde ẹ̀sìn, ni ìjọba fòfinde. Àwọn ọlọpàá sì tẹ̀síwájú láti máa mú àwọn ọmọ ẹgbẹ́, nípa lílo àfẹ́fẹ́ atajú láti tú àwọn olùwọde ká. IMN àti orísun ìròyìn náà jábọ̀ pé àgbára àlójú ti pọ jù, èyí tí ó fa ìfarapa àti ikú òjijì.

***Jàgídíjàgan ẹlẹ̀yàmẹ̀yà:*** Fún ọpọlọpọ ọdún, àwùjọ àgbẹ̀ àti darandaran tí dójú ìjà kọ ara wọn káàkiri ilẹ̀ Nàìjíríà, èyí tí ó ṣẹlẹ̀ jù ní agbègbè àárin gbùngbùn Nàìjíríà, láìsí èsì kan pàtó láti ọdọ ìjọba. Nítorípé àwọn ẹgbẹ́ náa ní wọn jẹ́ ẹ̀yà ọtọọtọ—pẹ̀lú àwọn Onígbàgbọ tí wọn jẹ́ Àgbẹ̀ pọ̀ǹbélé àti àwọn darandaran tó jẹ́ Mùsùlùmí—Àwọn ènìyàn agbègbè kọ̀ọ̀kan tún máa ń rò ìkọlù gẹ́gẹ́bí ìjà ẹ̀sìn. Ní 2017, ìjà láàrin àwùjọ darandaran àti àgbẹ̀ tẹ̀síwájú káàkiri orílẹ̀ èdè, àtipé ó lékún síi ní agbègbè gúúsù Nàìjíríà, tí .ó jà sí ikú, ìparun dúkìa, àti ìlénilááyè-ẹni. Fún àpẹẹrẹ, ní July, o lé díẹ̀ ní ọgbọ̀n ènìyàn ni ó kú nínu ìjà jàgídíjàgan ẹlẹ̀yàmẹ̀yà ní Kàdúná. Ìjábọ̀ kan ti November 2017 ní àkọsílẹ̀ pé Onígbàgbọ́ 139 ni ó kú ní Ìpínlẹ̀ Benue láàrin January sí August 2017. Àwọn ẹgbẹ́ ajàfẹ́tọ̀ọ́ ènìyàn jábọ̀ pé 549 ènìyàn ni wọ́n kú nínú ìja àgbẹ̀ àti darandaran káàkiri Nàìjíríà ní 2017, àtipé ẹgbẹegbẹ̀rún ènìyàn ní ijà náà lé láàyè wọn.

Aṣálẹ̀ àti ìjà ní àríwá orílẹ̀ èdè tí mú kí àwọn darandaran darí sí àpá gúúsù orílẹ̀ èdè. Bí àwọn àgbẹ̀ àti darandaran ṣe ń jà lórí lílo ilẹ̀ àti ibi ìdaranjẹ̀, jàgídijàgan ló máa ń já sí. Àlékún àwọn ohun ìjà ní igun méjèèjì, dídá ìròyín sí méjì, àti àìtó tàbí àìṣe déédéé àwọn òṣìṣẹ́ aláàbò tí jẹ́ kí ìṣòro náà burú jọjọ. Lákòókò àbẹ̀wò USCIRF sí Nàìjíríà ní 2017, àwọn àra ìlú àti àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba sọ oríṣiríṣi ìdí fún ìtàpórógan náà, bíi: ìjà ilẹ̀; awọn nǹkan ìjà olóró tí darandaran ń mú lọ́wọ́ láti dáàbòbò àwọn ẹran rẹ̀; Fulàni (ẹ̀yà tí ó jẹ́ pé iṣẹ́ darandaran ni olórí iṣẹ́ wọn) ti wọ́n ń gbẹ̀san ìkọlù wọn ní gúúsù Kadúná: àti àwọn àgbẹnusọ onígbàgbọ́, Aṣàfọ̀mọ̀ ẹ̀yà Fúlàni tó ń polongo ní ìlòdi sí ọmọ onílẹ̀ láti gba ìlẹ̀ wọn. Gbogbo wọn, àti Mùsùlùmí àti Onígbàgbọ́, sọ fún USCIRF pé wọn kò ní ìgbẹ́kẹ̀lé ààbò láti ọdọ̀ àwọn àláàbò. Wọ́n fi ẹ̀hónú wọn hàn pé ìdáàbòbò wà fún àwọn àṣèbi, àtipé tí àwọn bá pé fún ìrànwọ́ kí ó tó ṣẹlẹ̀ tàbí tí ó bá ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́, olọ́pàá kò ní wá.

Lẹ́yìn àkókò ìjábọ̀ náà, ìtàpórógan àgbẹ̀-darandaran àti awuyewuye ìjà ẹ̀yà àti ẹ̀ṣìn náà ń tẹ̀síwájú. Àwọn ìjábọ̀ nípa ìpolongo pípa ẹ̀yà rẹ́ ní ìlòdí sí àwùjọ onígbàgbọ́, pẹ̀lú orísírís orísun ìròyìn àti àwọn lájọlájọ tí wọ́n ní àwọn àrúfin náà ń wá láti ẹ̀yà fúlàni kanṣọṣọ. Àwọn olórí ẹ̀ṣìn àti ilé iṣẹ́ láti àwọn àgbègbè tí ó fara gbá ìṣẹ̀lẹ̀ yìí dá kú àwọn ìròyìn àhesọ nípa ìtàpórógan náà, nígbàtí àwọn mìíràn ń pé fún àlékún ìbáṣepọ̀ láàárín àwọn ẹlẹ̀ṣìn láti le gba àláàfíà láyè. Ní Nàìjíríà tí ẹ̀ṣìn tí múlẹ̀ ṣinṣin, ìdásí àwọn olórí ẹ̀ṣìn le ní ipa tó dára láàrín àwùjọ àti lórí àwọn àdarí òṣèlú.

Àwọn ẹgbẹ́ àjàfẹ́tọ̀ọ́, olórí ẹ̀ṣìn, àti àwọn ẹlẹ́gbjẹgbẹ́ láàrín ìlú tí tàko ijọba ài àwọn aláàbò fún kíkùnà láti fèsì tàbí dènà ìtàpórógan, tàbí fi arúfin jófin. Àní ọlọ́pàá to bí ó ṣe yẹ tí mú kí ìjọbá máa lo àwọn ológun náà láti pa òfin mọ́. Ní àwọn ìgbà yìí, ológun máa ńlo àlòjù agbára, pípa ara ìlú lára, wọn kií jẹ́ kí àwọn ẹlẹ́ṣìn ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú àwọn aláṣẹ mọ́. Ní àpẹẹrẹ kan ní November, agbébọn kan láti àgbègbè kan pa láàrin 30 sí 60 àwọn ọmọ ẹgbẹ́—tí ọ̀pọ̀ jẹ́ òbìnrin àti àwọn ọmọ wẹ́wẹ́—ní àgbègbè darandaran kan ní Kikan. Ní December, àwọn darandaran tí wọn dìhámọ́ra kọlú àbúlé kan pẹ̀lú èròǹgbà láti gbẹ̀san ní agbègbè Adámáwa, Àwọn ológun Òfurufu Nììjíríà sì di ìdáhùn ránṣẹ́ nípa yínyin rọ́kẹ́ẹ̀ti sí àwọn abúlé náà, èyí tí ó já sí ikú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ara ìlú àti ìparun dúkíà,

Ìjíròrò lórí ọnà àbájáde, gẹ́gẹ́bí ṣíṣàgbéga oko ìdaran aládani tàbí èyí tí ó máa wà lábẹ́ ìpínlẹ̀, níbití àwọn darandaran le ti máa fi ẹran wọn jẹ oko, àtipé sísọ fifi ẹran jẹko ní gbangba dí ohun tíko bá òfin mu mọ. Ní july àti October 2017, Ìpínlẹ̀ Taraba àti Benue ṣe òfin tí ó mú fífi ẹran jẹ oko ní gbangba jẹ́ ìwà ọdaran. Àwọn àwùjọ darandaran kan bẹ̀rẹ̀ sí ní sún kúrò láàrin ìlú nítorí èyí. Àwọn alátako sọ wípé irú òfin yi fí ẹ̀tọ àwọn darandaran dùn wọn Ní December, Gómínà Ìpinlẹ̀ Benue bẹ̀rẹ̀ fífi òfin náà múlẹ̀ nípa fífi ọlọpàá mú àwọn darandaran kan tí wọn sí máa gba ẹran wọn sílẹ̀.

***Boko Haram:*** Láti 2009, Boko Haram ti kò ìdàámú àti wàhálà bá àwọn ará ìlú, tí wọ́n sì ti pa 20,000 ọmọ Nàìjíríà, wọ́n jí ẹ̀gbẹẹgbẹ̀rún ènìyàn gbé, tí wọ́n sí lé bi mílíọ̀nù méjì láàyè wọn. Boko Haram ti ba ọ̀pọ̀lọpọ̀ Sọ́ọ̀sì, ilé, àti àwọn ilé ìjọba ní ìkọlù wọ́n tí wọ́n sì ti fi tipatipa ti àwọn ilé ìwé mìíràn pa. Ẹgbẹ́ náà ti pa tí wọ̀n sì ti pa àwọn ènìyàn lára nítorípé “aláìgbàgbọ́” ni wọ́n, àwọn olórí ẹ̀sì tí a mọ̀ kò gbẹ́yìn. Àwọn tí ìdáàmù yìí kàn jú ní àwọn obìnrin àti ọ̀dọ̀binrin, tí wọ́n ti fi tipatipa fi wọ́n lọ́kọ, tí wọ́n yí ẹ̀ṣì wọn padà tipatipa, ìfipabálòpọ̀, àti ìfiyàjẹni.

Ní 2017, Boko Haram ṣe àwọn ìkọ̀lù ju ti ọdún tó kọjá lọ, nípa lílo ọ̀pọ̀ àwọn aládò-ikú, tí ó jẹ́ pé ọ̀pọ̀ àwọn obìnrin àti ọmọdé ní wọ́n ń lò láti gbé àdó ikú náà. Láàrin ọdún náà, ẹgbẹ́ náà jábọ̀ pé àwọn pa, ó kéré jù, ènìyàn 300 ní Nàìjíríà, àtipé ó lé díẹ̀ ní ènìyàn 900 ní agbègbè Lake Chad. Ní May, Boko Haram dá àwọn ọ̀dọ̀bìnrin 82 sílẹ̀ nínú àwọn 276 tí wọ́n jígbé láti Chibok ní 2014, ní pàsípààrọ̀ fún àwọn olùja Boko Haram mẹ́fà. Àwọn bí 100 ní wọn kó rí mọ́ ní ìparí ìjábọ̀ náà, pẹ̀lú àìmọ́ye àwọn kan tí a kò mọ̀. Ní March, Boko Haram tún jí àwọn àwọn oìnrin 22 gbé àti àwọn ọ̀dọ̀binrin. Àwọn agbẹnusọ jàbọ̀ fún USCIRF lákòókò àbẹ̀wò 2017 pé ìjọbà àti àwọn àpèsè ààbò kò le pèsè ààbò tó pé fún àwọn ènìyàn ní agbègbè náà tàbí wọn kò fẹ́ pèsè ààbò tàbí wọn kò fẹ́ dásí ìṣòro ìjọ́mọgbé tó ń lọ lọ́wọ̀.

Pẹ̀lú pínpín Boko Haram sí ọ̀nà méjì ní 2016 tí igun kan ń ṣàtilẹyìn Abubakar Shekau tí èkejì ń ṣàtìlẹyìn Islamic State of Iraq and Syria (ISIS)-èyí tí Abu Musab Al Barnawi fọwọ́ sí, àwọn ìkọlù kan ní ISIS-West Africa ti gboríyìn rẹ̀. Ní 2017, irú ìkọlù ISIS-West Africa náà ni fifi àdó ìkú pa ni, àti pípa àwọn ọmọ ogun Nàìjíríà àti agbègbè àríwá Nàìjíríà.

Àwọn ológun Nàìjíríà ní ìlọsíwájú ní 2017 nípa gbígba àgbègbè kan padà àti mímú pẹ̀lú títú Boko Haram ká, ní apá kan lórí akitiyan ìsowọ́pọ̀ àwọn alámúlégbé Nàìjíríà, síbẹ̀ kó dá Boko Haram dúró láti ṣe ìkọlù àti ìpalára fún ará ìlú. Ó tún kùnà láti mú kí gbigba àwọn tí wọ́n jígbé lọ̀ ṣeéṣe. Àwọn ohun tó tún mú kí akitiyan àwọn ológun tún kùnà ni ẹ̀sùn tí wọ́n fi kan àwọn aláàbò pé wọ́n ń rúfin ẹ̀tọ̀ ọmọnìyàn. Ní October 2017, Àwọn ológun Nàìjíríà ṣí ọ́ọ̀físì tuntun sí Maiduguri láti le bójútó iru ìwàkiwà náà. Ilé Ẹjọ́ Agbẹ́jọ́ Ọdaran Àgbáyé ti ń ṣe àwọn ìwádìí ìbẹ̀rẹ̀ kan lórí àwọn ìwà ọ̀daràn tí ó lòdì sí ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn èyí tí Boko Haram àti Àwọn Ẹ̀sọ́ Aláàbò Nàìjíríà hù níwà.

Ní October 2017, àwọn ológun Nàìjírà bẹ̀rẹ̀ oríṣi ẹ́jọ àtẹ̀léra lórí àwọn afurasí Boko Haram 2,300. Gẹ́gẹ́bí ìjábọ náà, ó kéré jù, 468 nínú wọn ní wọn pàṣẹ fún láti kópa nínú èto ìsọraẹnidẹnirere.

***Ìgbófinró àti ìṣèjọba ẹ̀ṣìn ní ìpele ìpínlẹ̀:*** *Ìpínlẹ̀ méjìlá ní àríwá Nàìjíríà ní ó ń lo òfin* Shari'ah àtipé àọn kan ń lo ọlọ́pàa ẹ̀ṣìn láti ṣàgbéró ọlọ́pàá tó ti wà tẹ́lẹ̀ tàbí pèsè àwọn ìpèsè àwùjọ. Ìgbófinró Shari'ah àti lílo ìnáwó sí àjọ ọlọ́pàá ẹ̀ṣìn (tí a ń pè ní Hisbah) yàtọ̀ sí ara wọn láti ibi kan sí ibi kejì, bí àwọn ará ìlú ṣe faramọ́ sí tàbí ipa rẹ̀ náà yàtọ̀ láti ibi kan sí ibi kejì. Ní àwọn ìpínlẹ̀ kan figilanté tàbí àwọn ọlọ́pàá àdúgbò àti ọdẹ àdúgbò, bíi Hisbah, ní òfin wà fún. Ní ìpínlẹ̀ plateau àti kaduna, àwọn ará àdúgbo kan wà tí ó jẹ́ pé figilanté wọn dúró lórí ìlànà ẹ̀ṣìn, pẹ̀lú àwọn olórí ẹ̀ṣìn. Ní 2017, ẹnití ó bá jẹ́ ọ̀daràn, tí kò tẹ̀lé ìlànà ẹ̀ṣìn, tàbí ti ìùwàsí tó dára, ọlọpàá Hisbah máa mú, ó le fi sí àhámọ́ tàbí kí ó fún ní ìjìyàtó yẹ..

***Obinrin àti Òmìnira Ẹ̀ṣìn:*** *Lóòótọ́ òfin kò fààyègba ìfọmọdélọ́kọ ní Nàìjíríà pẹ̀lú òfi Ẹ̀tọ̀ ọmọdé ti 2003, tí ó fi ọjọ́ orí sí tó kéré jùlọ sí 18, ọ̀pọ̀ ìpínlẹ̀ ni kò tíì máa mú òfin náà lò. Gẹ́gẹ́bí ìjábọ̀ Àjọ Àgbayé, Nàìjíríà ní ọ̀pọ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ ìfọmọlọ́kọ lágbàáyé.* [Ìwọ̀n 46.8 nínú ọgọ́rùn ún àwọn obinrin Nàìjíríà tí ó jẹ́ ọmọ ọdún 18–49 ló lọ́kọ kí ó tó pé ọmọ ọdún 18], àtipé àwùjọ Fulani àti Hausa ni ó ní ìfọmọ́délọ́kọ jùlọ, èyí tí wọn gbà pé ó bá ẹ̀sìn wọn mú. Emir ti Kano, Lamido Sanusi II, jẹ́ ènìkán tí ó jẹ́ àṣiwájú nínú ìpolongo láti fòpin sí ìfọmọdélọ́kọ, àtipé ní 2017 ó gbìyànjú láti gbé òté lé iyé ọdún tó kéré jùlọ́ láti lọ́kọ èyí tí ó jẹ́ 17. O tún ń sọ̀rọ̀ nípa ẹ̀tọ obìnrín sí ètò ẹ̀kọ́ tí àwọn kàn kò sì fi ojú rere wòó.

**ÈTÒ ÌLÀNÀ U.S.**

Nàìjíríà jẹ́ kòkó nínú àwọn alábaṣe U.S ní Àfíríkà tí ó sì jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn àgbàrànwọ́ U.S tó tóbí jùlọ ní àgbègbè rẹ̀. Ní 2010, Ìgbìmọ̀ Ìbaṣepọ̀ U.S.-Nigeria (BNC) di dídá ṣílẹ̀ láti ṣàlékún agbára ìjíròrò láàrin orílẹ̀ èdè méjèèjì. Ní 2015, àtúntò de bá BNC pẹ̀lú ìfìjìn aláfojúsùn mẹ́ta ní àwọn agbègbè wọ̀nyìí: ààbò, ìdàgbàsókè ọ̀rọ̀ ajé, àti ìjọba tó dára. Ilẹ̀ Amẹ́ríkà ń tẹ̀síwájú láti máa pèsè àwọn ohun èlò ológun àti ìránwọ́ ọmọnìyàn pẹ̀lú ṣíṣètò ní ìbámu pẹ̀lú àwọn ohun tí ó ṣe pàtàkí ní Nàìjíríà, tí wọ̀n sí ń fẹ́ kí ìpamọ́ òfin ẹ̀tọ̀ ọmọnìyàn.

Ní 2017, ìgbá kèji Àkọ̀wé Ìpínlẹ̀ John Sullivan sọ pé kí àrídájú ìbáṣepọ̀ láàrin U.S àti Nàìjíríà lé wa, Nàìjíríà gbọ́dọ̀ fi ààye àti ṣewàdí ìlànà ètò ààbò rẹ̀ sílẹ̀ fáyé rí kí ó sì máa fi àwọn àrúfin lorí ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn jófin. O sọ ẹ̀yí ní [ìpaàdé November 2017 BNC] ní Abuja, níbi tí ó tún ti sọ pé ìgbógunti Boko Haram kò gbọ̀dọ̀ jẹ́ ti ológun nìkan ṣùgbọ́n gbogbo ọnà tó bá wà ní ó gbọ̀dọ̀ jẹ́ lílo. Ìgbá kejì Akọ̀wé Sullivan tún sọ̀rọ̀ lórí ìwúlò fún ìkẹ́kọ̀ọ́ àti ìjíyìn fún àwọn ẹ̀sọ́ aláàbò n;i [December 2017 ọ̀rọ̀ nípa ìgbogun ti adẹ́rùbàlú], lẹ́yìn ìgbà tó ṣàbẹ̀wò sí nàìjíríà.

Ìjọba U.S. sọ Boko Haram lórúkọ́ bí Afogundẹrùbàlú ní Ilẹ̀ òkèèrè ní 2013. Àwọn àṣojú aṣòfin rin ìrìnàjò wá sí Nàìjíríà ní August 2017 lati jẹ́ kí ìbáṣepọ̀ dán mọ́rán síi àti láti sọ̀rọ̀ níp ìjà ní ìlòdi sí Boko Haramto. Ní December 2017, the [U.S. National Defense Authorization Act for Fiscal Year 2018] ní ó di bíbọwọ̀lú sí òfin, pẹ̀lú ìpèsè ìlànà tí ó nílò kí ààrẹ sètò ìlànà láti ṣàmúdàgbà àwọn ilé iṣẹ́ ààbò àti ẹ̀ka ààbò ní Nàìjíríà, àti láti fà ìjábọ̀ kálẹ̀ fún Àwọn aṣòfin tí ó máa ní ìṣàyẹ̀wò lórí: ìhàlẹ̀ àti ewu tí Boko Haram àti ISIS-West Africa lé fà, àwọn akitiyan ìjọba

Nàìjíríà láti dáàbòbo ará ìlú àti ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, ètò fún Amẹ́ríkà láti le ṣiṣẹ́ pọ̀ pẹ̀lú Ọ̀ṣìṣẹ́ Nàìjíríà láti le ṣe ìwádìí àwọn ìrúfin ẹ̀tọ́ ọm\nìyàn tí àwọn ẹ̀sọ aláàbò Nàìjíríà bá ṣe àti ètò láti ṣiṣẹ́pẹ̀lú àwọn ìlé iṣẹ́ ààbò Nàìjíríà láti le ṣàmúdàgbà àwọn ipò àwọn tó wà láhààmọ́.

Ìbánikẹ́dùn nípa àwọn ìrúfin tí U.S ń ṣe aṣaájú rẹ̀ ní ó fa ìdènà títa ohun ìjà fún Nàìjíríà ní bí ọdún díẹ̀ ṣẹ́yìn, ṣùgbọ́n ní 2016 ìbáṣepọ̀ náà tún dán mọ́rán síi. Ní December 2017, ìjọba U.S fọwọ́sí mílíọ̀nù lọ́nà $600 fún títa ọkọ̀ òfurufú àti ohun èlò ogun. Ìdúnàdúrà náà jẹ́ ara ìfarajìn ìjọba U.S láti gbogun tí àwọn àfogundérùbálú ní Nàìjíríà àti ní Basin lake Chad ní ìlòdì sí Boko Haram àti ISIS-West Africa.

Láti ṣàtìlẹyìn ìjà ní ìlòdì sí ìkówó ìlú jẹ, Ilẹ̀ Amẹ́ríkà gba Nàìjíríà níyànjú láti darapọ̀ mọ́ Open Government Partnership (OGP), àjọ àgbáye tí ó fojúsun mímú kí ìjọbá dára síi, kí ó ṣeé jẹ́rìi, kí ó sì jẹ́ olùjàbọ́ fún ara ìlù, tí Nàìjíríà sì ṣe ní 2016. Ilẹ̀ Amẹ́ríkà ṣe ètò ìnàwó Àkànṣe iṣẹ́ tí ó mú kí ilẹ̀ Nàìjíríà ṣẹ̀dá èròńgbà OGP National Action Plan 2017–2019 tí ó ní ìfojúsùn ètò ìnáwó tí kò lábùkù, ìgbógun ti ìwà ìbàjẹ́, ìráyé sí fún ìwífún, àti ìṣàmúlò ará ìlú. Ní December 2017, Amẹ́ríkà àti Ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì jọ gbàlejò ìfilọ́lẹ̀ olú ilé iṣẹ́ Global Forum on Asset Recovery (GFAR) pẹ̀lú àfojúsùn láti ṣègbàpadà àwọn dúkíà tí ó ti di jíjígbé láti àwọn orílẹ̀ èdè mẹ́rin tó ṣe kókó èyí tí Nàìjíríà wà níbẹ̀. Ní 2017, ìjọba U.S. ṣe ìlérí láti ṣàtìlẹyìn fún àwọn olórí ẹ̀ṣìn láti gbogun ti ìwà ìbàjẹ́, nítorípé ó mọ rírì ipò wọn láwùjọ.